**Ọrọ agba**

ỌPẸRẸKẸTẸ ndagba, inu adamọ mbajẹ. Otitọ d'ọja o kuta, owo lowo la nreke; otitọ ni bori Irọ nkẹhin.


# Irohin Yoruba

NO. 125 WEDNESDAY NOVEMBER 25—TUESDAY DECEMBER 1 1964 KOBO MẸTA 3d

**Akiyesi**

POLOWO ọja rẹ ninu iwe 'Irohin Yoruba' Oloyinmọmọ ti o nta ni ọja bi akara gbigbona

# NI GBOGBO'GBA, UPGA Larin Tagba Tewe



OLOYE Adeniran Ogunsanya ti iṣe asoju kan pataki ninu awọn aṣaju ajumọṣepọ gbogbo ẹgbẹ Itẹsiwaju orilẹede yi-UPGA fi ohun ti iṣe ododo ọrọ gun Oloye S. L. Akintọla lara ni ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kọkanlelogun oṣu yi lori ewọn ti ile ẹjọ giga kan ni ilu Eko gbe Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ju si.

Ni ibi ipade ta gbangba ti Oloye Ogunsanya ṣe nẹlu awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA ni ọjọ na ni ọja Awolọwọ ni Mushin ni o ti fi ododo ọrọ na yọ.

Oloye Ogunsanya ṣe alaye ni ọjọ na pe awọn enia kan ti nwọn jẹ mayẹ iẹgbẹ ninu'ẹgbẹ Afẹnifẹre nigba kan ri ti nwọn wa parapo nisisiyi di omo ẹgbẹ Domọnu ni nwọn jẹ ẹlẹri pataki fun Ijọba ninu ẹjọ nla na ti Ijọba Apapọ ba Oloye Awolọwọ ṣe.

Oloye Ogunsanya ṣe alaye siwaju si pe ko si ọmọ ẹgbẹ Alakukọ kankan ti ile ẹjọ na pe lati wa jẹri ninu ẹjọ na, ati pe ẹgbẹ Alakukọ ko mọ-ọmẹsẹ pinnintin ninu jiju Oloye Awolọwọ sẹwọn.

O wa kilọ fun gbogbo ọmọ ẹgbẹ UPGA pe ki nwọn maṣe gbabọde awọn ọmọ ẹgbẹ Domọnu ti nwọn nforu boju kakiri lati bebẹ fun ibo wọn ninu idibo ti o de tan yi.

Oloye Ogunsanya faye awọn ọmọ ẹgbẹ UPGA ni ọjọ na pe gbogbo enia ti oruko wọn na ti han ninu iwe awọn adibo ni nwọn ni ẹtọ lati dibo iba jẹ pe nwọn ti sọ iwe eri oruko sile wọn nu.

**IṢẸGUN NLANLA**

Oloye Ogunsanya ṣe alaye pe na ki Oloye Awolọwọ ati Arẹ orilẹede yi, Dokita Azikiwe nupọ fun akitiyan won ti o mu ki orilẹede yi di ominira lọjọ oni; eyiti iṣe iṣẹgun nlanla fun won.

Ẹlomiran ti o fun sọrọ nibi ipade na ni Alhaji Yahaya Abbas ti iṣe aṣaju kan pataki ninu ẹgbẹ Onirawọ ti Oke Ọya lọhun. On na ṣe alaye pe o ṣe ki awọn enia orilẹede yi dibo lẹkunrẹrẹ fun UPGA nitoripe ti awọn enia ba ṣe bẹ, ilọsiwaju ni nwọn dibo fun.

Ni ọjọ Abamẹta yi kanna, UPGA tun ṣe ipade ita gbangba miran ni

(Wo oju ewe kẹjọ)

Laipe yi ni awọn aṣiwaju egbe Itesiwaju parapo wo Ipinle Ariwa bi oba. Bi awon enia Ipinle na ti nfi ijo ati ayo pade won ni nwon tun nfi orin aladun ṣe aponle won. Dokita M. I. Okpara, babasale egbe Alakuko ati Alhaji D.S. Adegbenro, adele babasale egbe Afenifere ni o ko awọn aṣiwaju UPGA lo si Oke Ọya na. awon aṣiwaju mejeji na ti pada de si Ipinle won.

Onirohin wa ti o ba won lo si irin ajo na ni o mu aworan oke yi bo fun awon onkawe IROHIN YORUBA lati ti bi omi ti ṣe tan lehin egbe Onikumo—NNA. Ilu Jos ni nwon ti ya aworan na.

**WU NNA TEGBOTEGBO**

## Mbadiwe gun Dọmọnu ni ọfa ọrọ

ẸGBẸ Domonu ti firu fonna lori ọrọ awon asaju egbe Alakuko meta ti egbe na so pe nwon nfi oru boju wa oju rere egbe Olomi ti Oke Oya pe ki o le fawon mora bi egbe na ba tesi gba aga Ijoba Apapo ninu idibo ti o de tan yi.

Ni ojo Eti ti ise ogunjo osu yi, okan ninu awon asaju egbe Alakuko meteta na, Dokita Kingsley Ozuomba Mbadiwe su egbe Domonu ati awon asaju re ni gbolohun oro longbekogbe lori oro na ti egbe Domonu ko ni le gbagbe lailai. Awon asaju meji yoku ti egbe Domonu fi enu re baje ni Oloye Dennis Osadebay ti ise Olotu Ijoba Ipin'le Agbedemeji Iwo Orun ati Alakoso Ijoba Apapo fun eto igbokegbodo Ise oko, Ogbeni Raymond Amanze Njoku.

Ninu oro Dokita Mbadiwe ni ilu Eko ni ojo na, o koko kei Oloye S.L. Akintola lahi enikan ninu awon asaju egbe Onikumo pe ki nwon yara tete so ti enu won fun araiye gbo bi o ba je pe enikeni



DOKITA MBADIWE

ninu awon meteta ti egbe Domonu daruko na ba se ipa'e maje agbo kankan pelu egbe Onikumo nibikibi ni orilede yi lori oro ti o jo idibo apapo ti o mbo yi.

Dokita Mbadiwe wa so bayi. "Ti ẹri ti o daju gede

(Wo oju ewe kẹjọ)

## Ọrọ Kotoyẹ ko to yẹ si—UPGA

AJUMỌṢEPỌ gbogbo ẹgbẹ Itẹsiwaju orilẹede yi-UPGA ṣe alaye laipẹ yi pe irọ patapata gba ni ẹgbẹ Dọmọnu pa nigbati o sọ pe awọn aṣaju kan ninu ẹgbẹ Alakukọ nforu boju wa oju rere ẹgbẹ Olomi ti Oke Oya nigbati apakeji ninu awọn aṣaju ẹgbẹ Alakukọ kanna gbogu ti ẹgbẹ Olomi yi nigbangba.

Ninu iwe ikede kan ti akowe ikede UPGA, Oloye Fred Anyiam fowosi ti o si gbe jade lati ile Ise egbe na ni Eko laipe yi, Oloye Anyiam se alaye pe Isokuso, abesi oro ati oro ontaye enia ni esun ti egbe Onikumo-NNA fi kan egbe Alakuko na je.

Oloye Anyiam tesiwaju ninu alaye re pe esun na ti egbe Domonu fi kan awon asaju meta ninu egbe Alakuko je ona ogbon jibiti ti awon akurete oselu ngba wa ona lati da yankanyankan sile Laria egbe Alakuko ki nwon le ri ohun se ẹsin oro ninu iwe Irohin orikede yi.

Oloye Anyiam se alaye siwajusi pe ohun ti o je Iyale-

(Wo oju ewe kẹjọ)

